«Mi o ni ki ẹ bura nítorí pé mo n fẹsun kan yin o, ṣugbọn Jubril wa ba mi o si fun mi ni iro pe dajudaju Ọlọhun ti O biyi ti O gbọnngbọn n ṣe iyanran pẹlu yin ni ọdọ awọn malaika

Lati ọdọ Abu Sa’ēd Al-Khuduriy o sọ pe: Mu’āwiya lọ sibi àpéjọ kan ninu masalasi, ni o wa sọ pe: Kini nkan ti o mu yin jokoo? Wọn sọ pe: A jokoo fun iranti Ọlọhun, o sọ pe: Ẹ bura pẹlu Ọlọhun pe nkankan o mu yin jokoo ayaafi ìyẹn? Wọn sọ pe: A fi Ọlọhun bura ko si nkankan ti o mu wa jokoo ayaafi ìyẹn, o sọ pe: Mi o ni ki ẹ bura nítorí pé mo n fẹsun kan yin o, ko si si ẹnikankan ti o wa ni iru ipo mi si Anabi - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - ti ẹgbawa hadiisi rẹ lati ọdọ rẹ (Anabi) kere to temi: Ati pe dajudaju ojiṣẹ Ọlọhun - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - jade si ibi akojọ awọn saabe rẹ, ni o wa sọ pe: Kini nkan ti o mu yin jokoo? Wọn sọ pe: A jokoo lati maa ranti Ọlọhun ati lati maa fi ẹyin fun Un lori bi O ṣe fi wa m'ọna si Isilaamu, ati idẹkun ti O fi i ṣe le wa lori, o sọ pe: «Ẹ bura pẹlu Ọlọhun ṣe nkankan o mu yin jokoo ayaafi ìyẹn?» Wọn sọ pe: A fi Ọlọhun bura ko si nkankan ti o mu wa jokoo ayaafi ìyẹn, o sọ pe : «Mi o ni ki ẹ bura nítorí pé mo n fẹsun kan yin o, ṣugbọn Jubril wa ba mi o si fun mi ni iro pe dajudaju Ọlọhun ti O biyi ti O gbọnngbọn n ṣe iyanran pẹlu yin ni ọdọ awọn malaika».

[O ni alaafia] [Muslim gba a wa]

Mu’āwiyah ọmọ Abu Sufyaan- ki Ọlọhun yọnu si awọn mejeeji- jade sibi akojọ kan ninu masalasi, ni o wa bi wọn pe kini nkan ti wọn tori rẹ kojọ, Wọn wa sọ pe: A n ranti Ọlọhun ni, Ni o wa sọ - ki Ọlọhun yọnu si i - pe ki wọn o fi Ọlọhun bura pe wọn o gbero nkankan nibi ijokoo wọn ati akojọpọ wọn yẹn ayaafi iranti Ọlọhun, Wọn si bura fun un, Lẹyin naa ni o wa sọ fun wọn pe: Dajudaju kii ṣe pe mo ni ki ẹ bura láti fi ẹsun kan yin ati lati ṣe iyemeji nipa ododo yin, lẹyin naa ni o sọ nipa ipo rẹ si Anabi - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - ati pe ko si ẹnikankan ti ipo rẹ sunmọ ọn - Anabi - to oun; latari pe Umu Habiibah ọmọ ìyá rẹ obinrin jẹ iyawo Anabi - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a -, ati pe o tun wa ninu awọn ti wọn maa n kọ waayi (imisi), tòun ti bẹ́ẹ̀ náà ẹgbawa rẹ fun hadiisi kere, Ni o wa sọ fun wọn pe dajudaju Anabi - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - jade lati inu ile rẹ ni ọjọ kan, ni o wa ri wọn ti wọn jokoo ninu masalasi ti wọn n ṣe iranti Ọlọhun ti wọn si n yin In lori ọna Isilaamu ti O fi mọ wọn, ti O si fi ṣe idẹkun le wọn lori, ni o wa bi wọn leere - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - ti o si tun ni ki wọn o bura bi iru nkan ti Mu’āwiya - ki Ọlọhun yọnu si i - ṣe pẹlu awọn eeyan rẹ, Lẹyin naa ni Anabi - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - wa sọ fun wọn idi ibeere rẹ fun ibura wọn: Oun ni pe Jubril - ki ọla Ọlọhun maa ba a - wa ba oun ti o si fun oun ni iro pe Ọlọhun ti O biyi ti O gbọnngbọn n fi yin ṣe iyanran niwaju awọn malaika, ti O si n ṣe afihan ọla yin fun wọn, ti O si tun n fi didaa iṣẹ yin han wọn, ti O si tun n yin yin loju wọn.